# EKO AKETE.

IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL I. No. 32. SATURDAY, FEBRUARY 17, 1923. FOURPENCE.



*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.


ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.


## N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street,*) EKO.





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWÓ. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

*(Macaulay's Household Dispensary.)*

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni ọpopo-nla (*Broad Street.*) l' Eko ni owo pọ o.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara, Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbog yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO. Ogun rẹ jẹ bi idan.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun ẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

---

## ỌGBẸNI DURỌ THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OṢUNTOLU, onişowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni No. 44. Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:— Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aṣọ oniruru, Itẹkọ, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini. (*Sallen.*)

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads (new arrivals from Germany) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to şeşẹ de fun u pẹlu awọn MAṢINI iranşọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mãse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

—:o:—

### AWỌN AGBA-AGBA MẸTA KÒRÒ-GBÀ-KÒRÒGBA NJUMỌ NLỌ SI'LE OLUYỌLE.

Gomina Agba, Kinniun Onibudo ati Lọya Jiga mu ọna-ajo pọn lọ si Ibadan ni ibẹrẹ ọsẹ yi: Gomina ṣi ni agogo mọkọnla oru *Monday* fun ati lọ ṣe ẹyẹ ti Ifihan-ohun ọgbin nibẹ, eyiti a ṣe ni ọjọ *Wednesday* ọjọ kẹrinla oṣu yi: awọn "Ẹbọra" meji to ku jọ ṣi ni arọ ọjọ *Tuesday* fun iṣẹ tiwọn nibikanna. Ọna 're o, ẹnyin ọkunrin-ti-a-fi-nṣepe ọkunrin.

---

### DẸ-DẸ O, ẸNYIN AṢOJU-ỌBA LỌNA AJIDO.

Ihin kan ni lati Badagry laipẹ pe gbogbo awọn enia ti nwọn nna ọja bi Omfo, Ọbada, ati Agada ati ilu ṣẹ-ṣẹ-ṣẹ miran labẹ Ilaro lo ntuka fi ile ati ọna wọn silẹ nitori owo-ori ti Ijọba ngba lọwọ olukuluku wọn ti a sọ pe o pọju, ti a si sọ pe o nni wọn lara: ati pe a tun mbu owo geregere fun wọn ni sisan ti nwọn ko ba tete san owo-ori na: ati pe a tun sọ ti jãdi ti awọn oniṣẹ-ọba bi awọn "ọmọ-iṣẹ" (*Messengers*) nṣe awọn enia wọnyi nipa kiko ọja wọn lalai sanwo rẹ: a sọ pe iyà ti a fi njẹ awọn enia wọnyi npọ lorişirişi rekọja àla. Ti gbogbo ọrọ yi ba ri bẹ, a ke si Ọgbẹni wa Henry Carr, Ab'ọwọ-gbọgbọrọ ti nyọ'mọ-rẹ-lọfin. Balẹ Ọkọ Ilu ẹniti awọn ilu yi wa labẹ aṣẹ rẹ, ko ma ṣai wadi ọran na finnifinni, ki o si "rẹ awọn ọmọ rẹ wọnyi lẹkun."

---

### KABỌ, ỌMỌ ANAWO-BI-ẸLẸDÀ.

A ki Ọgbẹni Hutton Mills, Lọya, ọmọ Thomas Hutton Mills ọlọla ti Accra "kabọ" si dide rẹ si'lẹ yi ni ọjọ *Thursday* ọsẹ to kọja ninu ọkọ "Ada-baba-ọbẹ." Ẹnyin ọkawe wa yio ranti pe baba Lọya yi lo bu ẹgbẹrun-pọnwun-ole adọta lu apò ẹgbẹ *Congress* nigbati a kọkọ da Ẹgbọ na silẹ ni Accra ninu oṣu *March* ọdun 1920.

---

### IKU TO PA PORTER NPOWE!

A ba Ijọba wa kẹdun iku Ọgbẹni Oyinbo C. Hornby-Porter, Oniṣẹ-ọba to ṣẹlẹ ni ilu *France* ni iwọn oṣu melo to kọja: Ọgbẹni yi lo pin Ẹbun ati Iwe-ẹri fun awọn ọmọ-ile-iwe giga ti Ode Ondo l'eşi nigbati o wa lẹnu iṣẹ nibẹ. A ro pe ẹnyin ara ilu yio si ṣe iranti pẹlu bi o ti nṣa owo mọ awọn onigun-ku-gun kẹkẹ-ologere lara nigbati o nṣe Adajọ kekere nibi ninu ọdun 1911. O mbu pọnwun meje-abọ (£7. 10.) fun ẹlomiran ni sisan.

---

### Ẹ ṢEUN, AKỌWE KỌ WURA !!!

A gbọ pe awọn Akọwe ti Ile-òwò John Holt ni ilẹ yi ngbara-di lati ṣe bẹbẹ fun ọkan ninu awọn Ọga agba wọn ti o jẹ ọkan ninu awọn ọmọ oniṣowo na eyini ni Oyinbo Ọgbẹni Robert Holt fun bibẹ to wa bẹ Ile-òwò na wo lọdun ni. Ọgbẹni J. Mọṣalewa Thomas ọkan ninu awọn Akọwe na alakikanju lo njù-sihin-jù-sọhun ki gbogbo imura na le ṣe rẹgi. Nkan a "ṣ'ẹnu-re" laipẹ.!

---

### INA GORI ILE F'ẸJU!

Ina nla kan ṣẹlẹ ni Badagry ni ọjọ keje oṣu yi: a gbọ pe iwọn ọgọrun ile lo jo ti ikin ti panu. A dupẹ lọwọ Oyinbo Ọgbẹni Whyte fun ayan to ṣe pẹlu awọn "lebira" rẹ lati gba ina na: Oyinbo yi jẹ Aṣoju awọn oyinbo onişowo Epo, Agbọn ati t'ẹpa (*African Oil Nuts Co.*) ti ilẹ yi.

---

### ỌDUN AWẸ TI "ONIBÙKÚ."

*Wednesday* ọsẹ yi jẹ ibẹrẹ Ọdun Awẹ ti awa "Onibuku" ti a npe ni *Wednesday* Eru. Gbogbo Ile-isin ni yio si ma ṣe isin ṣoki ni alẹ ọjọjọ-ọsẹ yi, a fi awọn Ile-isin diẹ.

## Ẹ KU "A-T'ỌRUN-BỌ" AKEWUṢỌLA.

A ṣi Ọgbẹni wa Adam Idris Animaṣaun "kabọ" lati Ile-ihamọ ti o ti lọ lati lile ni oṣu mẹta wa. Ọgbẹni na jade larọ yi, ọgọrọ awọn Janman ati awọn abani-kẹdun miran lo lọ pade rẹ. Agba to r'ejo ti ko sa, ara iku lo nya a!!!

## A BỌ O, ỌMỌ GBADEṢERE!

A ba Ọgbẹni Lawson yọ fun ikókó ti aya rẹ fi ta a lọrẹ ni *Saturday* to kọja: a si ba *Xander* wa (Dr. Oguntọla Ṣapara) baba iya "alejo" na yọ pelu: "Eko r'ohun fẹ" ni ọmọ na: a sọ pe ni ọjọ kanna ti a gbe Mary ọmọbinrin kanṣọṣọ ti Ọba *King* George ni ilu Oyinbo niyawo, ọjọ na gan ni a gbe 'Mọlara iya ikókó na niyawo fun Ọgbẹni Lawson. Ninu "Waya" (*Reuter's Telegrams*) to de ni *Saturday* to kọja a gbọ pe Mary ọmọ-alade na fi ikókó (ọkunrin) ta ọkọ rẹ *Lascelles* lọrẹ, ọjọ kanna ẹwẹ si tun ni aya Ọgbẹni Lawson ti a nwi yi bimọ tirẹ. Njẹ, awa sọ ọmọ tiwa nibi ni GBADERO. A to olorukọ rẹ o!

## GÀSÀ!!!

*Motor* pupu kan ti a npe ni *Harley Davidson* kẹkẹ-ologere £600 ti Oyinbo kan gun lọ si ọna *Porto Novo Market Street*, lapa ti awọn Oyinbo C.B.C.A. ṣe ọkunrin "ara oke" kan lẹṣẹ ni arọ *Wednesday* ọsẹ yi nipa fifọ ọ lẹṣẹ ọtun tùtù: ọgafa, a fi *Motor* alaru kan L572 gbe okunrin na lọ si Ile-alarun, a si rà Oyinbo na mu lọ si "Ṣabu" ọlọpa.

## BẸNI TIRẸ RI, ỌMỌ LIṢABI!

Inu wa dun pupọ lati gbọ pe Ẹni ọwọ M. S. Cole Alufa Ṣọṣi Alagogo npete ati ma ṣe Iwe-irohin nipa Isin, ninu oṣu to nbọ. A gbọ pe oṣoṣu ni Iwe-irohin na yio ma jade, orukọ ti a si sọ ọ ni *The Cathedral*, yio si jade ni ọjọ 27 oṣu *March* gẹgẹbi a ti gbọ. A o ma ṣe afoju-sọna "ẹni titun" yi.

## IGBẸ L' OWO WÀ.

### EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Idapọ-Owo (Niger Co., C. W. S., McIver, African Eastern Trading Corporation, Jurgens Colonial Products, John Walkden.) £11 10 de £12 10 fun *ton* kan

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co,) bakanna.
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores) do.
Miller do.

### EPO.

£21 10 de £22 10 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

### COCOA.

Lati £24 de £25 fun *ton* kan bakanna.

---

Irohin kukuru ti Ile Isin Saint Stephen nipa fifi Ọgbẹni Jonathan Tubopiribọ Epelle jẹ oye Diakoni ni ọjọ kọkanla oṣu yi ni agogo mẹsan.

Isin yi bẹrẹ ni agogo mẹsan abọ orin (3) kẹta ti Ijọ yi ni awọn ẹgbẹ akọrin kọ wọ inu ile lati ẹnu ọna nla. Awọn ẹni ọwọ Patriarch J. G. Campbell, Apostle Ijaoye ati Epega lo ṣe isin yi.

Nipari orin kẹta, ni gbogbo ijọ kunlẹ lati kọ orin "Emi l' Ọlọrun" lẹhin na Ẹni-ọwọ Apostle Ijaoye ka Idapọ Mimọ ati adura Epistle ti ọjọ oni iwe kini Korinti ori kẹtala bẹrẹ ni ẹṣẹ kini ati Ihinrere ti a kọ lati ori kejidilogun Saint Luke bẹrẹ ni ẹṣẹ kọkanlelọgbọn.

Igbagbọ ti Nikia

Ẹni ọwọ Patriarch ṣe ifilọ wipe ni agogo mẹta ọsan yi ẹni ọwọ Apostle Ijaoye ma ṣe ifi ẹnikan joye Diakoni ni Ile Isin Jehovah Shalom Church, Ṣiṣi Ile Isin ni Ebute Mẹ-

ta ita Kadara ni ọjọ *Thursday* ago mẹta ọsan, isin yio wa ni ijọ yi ni ago meje abọ ni alẹ *Wednesday* ti a npe ni "*Wednesday Eru*" (Ash Wednesday) ati wipe isin yio wa ni ijọ yi lagogo meji ọsan loni fun isami Ẹni-ọwọ Epega lo ma ṣe iwasu kukuru Ẹni-ọwọ Epelle ti a fi joye larọ yi yio ṣe iwasu larọ ijọ mẹjọ loni ijọ kejidilogun oṣu yi.

Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Epelle wa si iwaju lati fi ibere si iwaju rẹ, lẹhin na ẹni ọwọ Campbell pe orin (81). Ẹni-ọwọ Campbell ṣe iwasu, ọrọ rẹ lomu ninu ihinrere ti Mattiu ori kejidilọgbọn ẹsẹ kọkandilogun ati ogun ọrọ na to wipe :—

"Nitorina ẹ lọ, ẹ ma kọ orilẹ-ede gbogbo, ki ẹ si ma baptisi wọn li orukọ Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmi Mimọ : ki ẹ ma kọ wọn lati ma kiyesi ohun gbogbo, ohunkohun ti mo ti pa li aṣẹ fun nyin ; ẹ si kiyesi i, emi wa pẹlu nyin nigbagbogbo, titi o fi de opin aiye. Amin."

Nkan to mu mi kọ ọrọ yi silẹ nipe, ẹnikẹni to ba gbọ iwasu yi, ni ede Yoruba, Oyinbo ati Ibo to fi ṣe wasu ti ko ju iwọn iṣẹju mẹdogun lọ pẹlu itumọ ọrọ wọnyi, ori a ṣi, iṣẹ oniwasu a wun enia ṣe.

Ọgbẹni Epelle wa siwaju nipari iwasu yi fun ibukun ati fi jẹ oye. Ẹni ọwọ Campbell pe orin ogun (20) lẹhin eyi ni a fi iwe aṣẹ ati Bibeli le ni ọwọ, gbogbo ijọ kunlẹ wọn si gba adura iṣẹju marun le lori nipa ijọ kọrin (57) iketadilọgọta ni ikunlẹ.

A gba ẹni ọwọ Epelle si agbo awọn alufa, on lo pe orin akọgbẹhin (24) kẹrinlelogun, awọn ẹgbẹ agbowo bọrẹ si owo gba.

Awọn ẹgbẹ akọrin kọ orin ọgọrun (100) bi wọn ti nto jade lọ, lẹhin ti gbogbo ijọ jade ni awọn diẹ ninu awọn to le duro ṣe isin ipin fun ni Onjẹ Alẹ Oluwa, isin pari ni ago mọkanla kọja iṣẹju mẹdogun.

Ẹni ọwọ Jonathan Tubopiribọ Epelle jẹ ọmọ ti Patriarch Campbell duro fun ninu isami rẹ, on kanna lo tun fi jẹ oye yi, iṣẹ Ọlọrun tobi pupọ, ẹni ọwọ yi pẹlu Patriarch yo fi ilu silẹ ni ijọ kọkandilogun oṣu yi bi wọn ba ri ọkọ lọ si ibi iṣẹ ti Ẹni ọwọ yi la jibin iṣẹ rere rẹ ni *Queenstown*, Andoni Ikpa ti Opobo District.

Ki Oluwa ko ba ẹ lọ. ki Ẹmi to ni lati fi ara rẹ jin fun iṣẹ yi ko ma kuru, Jesu dahun o si wipe "Ẹ si kiyesi i, Emi wa pẹlu nyin nigbagbogbo, titi o fi de opin aiye" Oluwa na a wa pẹlu rẹ. Amin.

ALAFOJURI

---

## ALỌ.

### IDARAYA AWỌN ỌMỌDE.

Alọ o,

1. Ngmm.
2. O nlọ si Ọyọ, o kọju si Ọyọ, o mbọ Ọyọ, o o kọju si Ọyọ.
3. Ojo pa Lukọtun, ko pa Jaguna.
4. Aja mi ṣẹkẹrẹ-ṣẹkẹrẹ ṣẹ, aja mi ṣẹkẹrẹ-ṣẹkẹrẹ ṣẹ, ojumọ ki imọ, ki o ma jẹ adiẹ funfun.
5. Ka mu ragba-ta-ragba, ka mu ragba-ta-ragba ka mu ragba ka fi takuta gba.
6. Agba meji duro li etido a ko mọ ẹgbọn a ko mọ aburo.
7. O ku atọdunmọdun, o ku atọdunmọdun a ba li oke odo o nfẹyin kẹ ẹ.
8. Iyawo rọgbọdọ a ṣowo ma wọ ile.
9. A bẹ lori, a bẹ lọrun, o ni on ka ṣai jẹ oye baba on.
10. Obinrin rọgbọdọ larin ẹgun.
11. Oruku tindi-tindi oruku tindi-tindi oruku bi igba ọmọ gbogbo nwọn jẹ atiro.
12. Ṣẹṣẹ ni igbo, wọwọ ni ọdan, gere li apata, Ọpọnti ko ni oru, Ajigun ko ni apata, Ọṣepọ ko ni ata, Ọranwu ko li kẹkẹ: meje la pa a meje la ja a.

### AKIYESI.

(a) Ki ẹnikẹni to ba fẹ fi esi ṣowọ fi (3d.) torọ ṣowọ pelu.

(b) Ka kọ esi si oju iwe kọkan ko si yanju.

(c) A fẹ awọn ọmọde lati ọmọ ọdun mẹwa de ọmọ ọdun mọkandi-logun lati sure ije yi.

(d) A fi aye silẹ titi arọ ọjọ kinni oṣu *March* 1923, lati gba gbogbo esi, a o si tẹ orukọ awọn to ba jagunmolu sinu Iwe-irohin wa ti ọjọ kẹta oṣu *March* na.

Ẹbun kini 5/- Ẹbun keji 3/-6 Ẹbun kẹta 1/-6

Kẹ fi esi ṣowọ si Arapaṣọwu,
c/o Editor, EKO AKETE.

# EKO AKETE.

EKO, SATURDAY FEBRUARY 17, 1923.

## OMI TITUN, ẸJA TITUN.

Ọrọ ti a gbẹnule ninu iwe-irohin yi ti ọjọ kẹsan oṣu *December* to kọja, nipa ti Igbimọ Aṣofin-Ijọba titun ti Gomina-agba Sir. Hugh Clifford oloye nla G.C.M.G. ndaba lati da silẹ ṣẹ fẹ jalẹ lọdunni. Ẹ o ṣakiyesi pe a sọ nigbana pe Gomina npete ati pa Igbimọ-Aṣofin ti o wa nisisiyi, ati Igbimọ ti Nigeria rẹ, eyiti Lugard Gomina-Ologun da silẹ larin wa nibi ni ọjọ keji oṣu *November* l' ọdun 1913—o le ni ọdun mẹsan nisisiyi.

Gbogbo wa ti o nṣakiyesi ọran Ilu lati iwọn ọdun kẹta wa, ko ni ṣaimọ pe ninu ọdun 1920 ti a kọ ṣe ipade-nla ti gbogbo Enia Dudu (*Congress*) ni ilu Accra, ni a ṣe Ipinnu pe o to akoko ti awọn Ijọba iba ma fun wa laye lati ma jẹ ki ara Ilu ma yan awọn ẹniti nwọn ba fẹ sinu Ajọ-Igbimọ-Aṣofin ti Ijọba, lati ma ṣe oju wa nibẹ fun ohun gbogbo ti a ba nfẹ, tabi eyiti a ko ba fẹ: nigbati a si tẹ Ipinnu yi ko si ẹnikan ti ko ri i ka ni gbogbo aiye: a si dupẹ pe, biotilẹjẹpe Gomina Agba sọ pe ki nṣe nitori ọrọ ti *Congress* sọ si Atunṣe yi lo mu on lati fẹ fun wa ni anfani na, sibẹsibẹ a ko ṣai mọ pe ati suke enia ko ṣẹ'hin lakuregbe.

Gẹgẹbi a ti wi ni iṣiwaju, Gomina ntanmа ati "ṣe ṣawura" ohun ti o jẹjẹ yi, bi a ti ri i ka ninu Iwe-irohin Ijọba (Akanṣe) ti ọjọ kẹwa oṣu yi: nibẹ, a kede pe ipade yio wa ni agbala Ile-iṣẹ Ilu (*Nigerian Secretariat*) ni agogo mọkanla arọ ni ọjọ 26 oṣu yi, o bọ si ọjọ *Monday* tabi Atini: nigbana ni Gomina yio sọ ti ayipada nlanla ti yio wa fun titọju Ilu Nigeria a sọ nijelo pe a yọda fun wa l' Eko lati yan ẹni mẹta ti yio jẹ "Giriki" sinu Ajọ Igbimọ-Nla yi, a si yọda fun Ilu Calabar lati yan enia kan: boya, a le ri awọn miran ti nwọn yio ṣaroye pe iye awọn enia yi ko de 'bikan rara: ṣugbọn ki oluwarẹ na mọ pe kerekere ni eku nj' awọ diẹdiẹ ni imu ẹlẹdẹ nwọ ọgba; ati pe eni l' a kọ ṣe k' a to ṣe eji. Ipade yi ṣi silẹ fun ẹnyin ara ilu lọkunrin, lobinrin lati lọ. A si tun tẹnumọ ọ, gidigidi pe ki a ri pupọ ninu wa ti yio lọ sibẹ: eyi yio ṣi Gomina lori ati Ijọba pẹlu pe awa onilu ṣẹ nni ifẹ si ohun ilọsiwaju ilẹ wa: bẹni irufẹ ifẹ yi ko ṣai si l' ọkan olukuluku wa, ṣugbọn ọpọlọpọ enia ni ko mọ pe Ilu le lọ sinu ipade Ijọba bi eyi, nwọn ro pe ẽwọ ni: eyi ko ri bẹ, rara.

Nigbati Gomina yio ṣe ipade ti Nigeria aṣekẹhin ti a wi yi lọjọ na, yio sọ pe ofin titun ti Igbimọ-Nla ti a nsọrọ rẹ na, yio wọ'lẹ ni ọjọ ekinni oṣu *June* lọdunni: a o si pe apejọ ekinni ti Igbimọ titun na ninu oṣu *October* lọdun kanna.: Ara Ilu, a bẹ nyin tẹlẹ, fun rere gbogbo wa, ẹ fi ọjọ ipade na s' ọkan, ani ọjọ kẹrindilọgbọn oṣu yi, ni agogo mọkanla arọ, ki a si ri ọgọrọ ninu wa ti yio lọ; nwọn kĩ mu ni silẹ nibẹ! ẹ si jẹ ka fi ati isisiyi ma f'oju sun awọn enia mẹta ti a o yan, nigbati akoko ba to. A ki ti ọjọ ogun w'ẹfọn: o si yẹ pupọ ki irẹpọ ko wa larin wa fun iṣẹ-tiantian yi: bi a tilẹ ni gbún-gbùn-gbún kan si ara wa, o yẹ ki a pa a ti, ki a f'ẹjẹ sinu ki a tutọ funfun jade, nitori ati le "gba Iyawo" titun na. A ba gbogbo Ilu Nigeria yọ si ori're yi, ki Edumare jẹ ki eyi to ku ninu eto Ajọ Igbimọ Aṣofin ti a nsọrọ rẹ na le ṣe oju wa l' atari anfani.

Ba o ku, iṣe o tan.

---

### WESLEYAN DISTRICT SYNOD.

The Annual District Synod of the Lagos District of the Wesleyan Methodist Church opened its session at Trinity Church, Tinubu Square, under the Chairmanship of the Revd. Oliver J. Griffin with the singing of the time honoured hymn.

And are we yet alive,
"And see each others face."

After Devotional exercises the Chairman welcomed the brethren and received the felicitations of the Synod. Two members of the pastoral session were absent, the Rev. L. R. Potts Johnson who has so distinguished himself in the course of study that he is taking in England that the Home Committee have suggested that the Synod should grant him a further year of absence. The other absentee was the veteran Minister the Rev. S. P. Johnson who is no longer equal to the strain of meeting daily in Synod. The Synod sent an affectionate message to him expressing the hope that he might feel himself strong enough to visit the Synod during its session. Mr. Johnson, it is interesting to note is a link with the days when the circulation of coin was so restricted that it was neccessary to pay minister's stipends in kind.

The annual letter of the Committee to the Synod was then read. The Committee have strengthened the staff of the District during the year by appointing three new Missionaries, the Rev. J. Allan Angus to the Wesleyan Boys' High School, Miss Shovelton to womens work in the interior and Miss Liony as nursing sister at the Wesley Guild Hospital at Ilesa. Miss Shovelton's appointment marks a new departure in the work of the District and it was agreed to send a letter to Miss Shovelton assuring her of the Syond's sense of the importance of her work and of their interest in it.

It is a peculiarity of the Wesleyan Methodist Church, that each minister is required to make an annual declaration of his adherence to our doctrine and discipline, and that each ministers character and ability for our work has to be certified annually by his colleagues. The remainder of this session and the two following ones were taken up with these questions and with routine business.

On Sunday, special preachers from the interior occupied all the Wesleyan Pulpits in Lagos, and during the week "Trial Sermons" are being preached by candidates for the Ministry and candidates for Ordination.

On Tuesday, the Synod met in Representative Session, the heart of Thomas Birch Freeman the first Protestant Missionary to carry the Gospels to Nigeria would have rejoiced to see the Representatives of the Abeokuta Circuit, his first station, taking their seats with the representatives of the other self supporting and self controlling circuits.

Mr. E. A. T. A. Johnson was appionted to act with the Chairman as auditor of the accounts, the first African to hold this appointment.

A letter was read from the Secretary of the National Congress of British West Africa asking for the special prayers of the Church during the session of their conference in Freetown. Dr. Obasa said that although he was well known as differing from the promoters of this congress on points of management he was in the fullest sympathy with its aims and aspirations and he considered that the Synod would be failing alike in its duty to Africa and to Christianity if he did not accord with this request. Mr. P. J. C. Thomas warmly seconded him and the Synod agreed.

The Chairman read a letter from the Rev. William Goudie written shortly before his death commending the work of the Native Races and Liquor Traffic Association to the generosity of the Church it was agreed to make arrangements to give this Association such financial assistance as was within our power.

The Chairman also annouced the formation of a Wesleyan Methodist Chistian Literature Society for West Africa, with a view to providing suitable text books for use in our schools and also general Christian Literature. The Rev. W. T. Balmer M.A. B.D., has been set aside for this work and will be visiting Nigeria in March.

A letter was read from the Liverpool Wesleyan Mission intimating that they were undertaking work among West African Seamen and others in Liverpool, a Pastor has been set aside for the needs of these men, special premises are being opened for their accommodation and entertainment and it was desired that we should make this work known as widely as possible to Africans visiting England. The Chairman remarked that already he had brought to his notice the case of an African who had been converted to God by the Ministry of this section of the Mission and who was now returning to Africa with his wife and family after an interval of eight years, and was eager to help in our work. Mr. Thomas remarked that while the suggestion of partronage must be rigorously excluded there was a tremendous need for such work and both he and the Chairman urged the Synod to see that young Africans proceeding to the United Kingdom were provided with the introductions to suitable people. The Chairman observed that this work was receiving the special attention of the Mission House which had set aside a room at Bishopsgate for the use of African Students and others in London, and that if the machinery in existence were only used by the parents and friends of Africans going to England there was no reason why any African should be without friends in any of the big cities.

The remainder of the session was devoted to a statement of the position of our scheme for enlarging our training work at Ibadan. The Synod shewed clearly its opinion that no consideration must be allowed to delay the putting into effect of our plans and the matter was still under consideration when the Synod adjourned.

---

*Calabar 22, 1. 23*

## IRIN AJO LATI EKO LỌ SI KAMAROON.

Ni agogo mẹrin abọ irọlẹ, ọkọ elefin *Elmina* ṣi ni ebute *Marina*, lati lọ si Bonny, Port-Harcourt, Calabar, Victoria ati Duala.

Ẹnikẹni ko ni ireti pe ọkọ yi yio de si ilu Eko ni ijọ *Friday* na, eyiti iṣe ọjọ kọkandilogun oṣu Gẹgẹ bi agogo oke ti fi wakati kan ya ju ti ọkọ lọ, agogo mẹrin abọ yi jẹ marun abọ ti Eko.

Bi agogo ọkọ ti nde ori mẹrin abọ, bẹni ọga ọkọ lu ago si awọn awakọ ti o wa ni isalẹ pe o ya, warawere nwọn ti tu ọkọ l'ara ibiti nwọn gbe de e mọ, olukuluku ero ni funfun ati dudu si nju aṣọ funfun si awọn ojulumọ ti o sin wọn wa si Ebute.

Bi akoko yi ti jẹ akoko ti a ni lati mu "Tea ọsan," a nfi ọwọ kan jẹun a tun nsare lọ yọju lati ki awọn ara wa lori Kereni, nitori bi enia jafara ati fi tea tẹ 'nu, o si tun di alẹ niyẹn.

Ni iwọn agogo mẹta abọ ijọ *Saturday*, a de Bonny, awọn ero Bonny bọ silẹ, a si ko ẹru ti o wa fun awọn onisọwo silẹ pẹlu. Ni Bonny, ọkọ ki ilọ si ara Kereni, yio duro si arin om ni, ibẹ si jẹ ọsa, a ko ti fi okun silẹ lati wọ ọsa Bonny lọ. Bi a ti de Bonny bẹni awọn oyinbo onisọwo wọ ọkọ igbaja wọn wa sinu ọkọ lati wa ṣere diẹ ninu rẹ.

Ni iwọn agogo marun la ṣi kuro ni Bonny o di Port-Harcourt, a ko le de Port-Harcourt ni alẹ na, ọkọ wa duro ni iwọn agogo meje larin Bonny ati Port-Harcourt. Ni arọ kutukutu ọjọ *Sunday* ni iwọn agogo marun abọ, ọkọ ṣi, o di pitipiti, nigbati o fi ma to agogo meje kọja, a de Port-Harcourt, ọkọ si lọ si ara Kereni

Nigbati a ti jẹun tan l'arọ na ni iwọn agogo mẹjọ abọ, mo bẹ silẹ lati lọ rin ilu na wo, Kereni Port-Harcourt gun pupọ, ọsa rẹ si jin, ilu papa wa lori oke, ilu na tobi, o si jọ station reluwe *railway* pupọ, awọn ile wa ṣẹ-ṣẹ-ṣẹ kakiri, ko si sunmọ ra wọn rara, ile awọn akọwe ti o wa nibẹ ri kutupẹ-kutupẹ, yara kan Parlour kan ni, olukuluku si ni lati tun ṣe fun 'ra rẹ ni.

Ni ago kan ọsan, ọkọ wa ṣi ni Port-Harcourt, bo ti kuro lara Kereni, o tan, ki a to tun le ṣi kuro nibe o to agogo mẹrin, o wa gba o fi mọ ọna, o tun di Bonny, o de Bonny ni agogo meje nlọ lu, o si tun sun nibẹ, ngbati o di arọ kutukutu *Monday*, ọkọ wa ṣi, o mu ọna Calabar pọn.

Ni ọjọ *Monday* na, ni iwọn agogo mejila fi iṣẹju mẹdogun kọja, ọkọ fun fere idagiri, olukuluku wa si lọ sidi ọkọ igbaja ti yio ba sa asala bi ewu ba de, nigbati o si di agogo mejila abọ, ọkọ fun; olukuluku wa si tuka, larin iṣẹju mẹdogun yi ninu ile ti a gbe wa, awọn ole pa Sinbi aya Adewale ati Ṣubuọla aya onifọto *Photographer* ọgbẹni Aileru l'ẹpa, nwọn ko nwọn l'aṣọ, kaba olowo l'ori ati aṣọ sanyan t owo rẹ ga, nwọn ṣe iyọnu titi ṣugbọn a ko fun wọn ri.

Ni alẹ *Monday*, ni iwọn agogo mẹfa abọ, ọkọ wa gun si ebute Calabar, nigbati awọn onibode si ti wa sinu rẹ, o wa lọ si ara Kereni.

*Koiti pari* AJEJI

---

## ORIN NI OHUN ILẸ WA.

Ijọ ọmọ ibilẹ ati Ijọ Iṣọkan gbogbo ẹda, ti o wa ni igboro Eko l' oni nfi han ni pe ki iṣe ẹṣẹ lati ma kọ orin ni ohun ilẹ wa ninu ile Ọlọrun l' akoko isin mimọ. Ni sa a kan, a ka ohun orin ti ilẹ wa si ẹṣẹ, nigbati a gbe eto isin ti awọn t' o mu isin Ọlọrun lati ilu ajeji wa fun wa, kanri. Ki nto lọ siwaju, o yẹ ka ṣakiyesi wipe iyatọ wa ninu orin ati ohun orin. ohun orin ti abọriṣa nlo, imale le kọ ọ; gẹgẹbẹ ni onigbagbọ si le lo ohun orin kanna. Iyatọ ko si ninu ohun (air) ti a fi nkọ orin, bikoṣe awọn ọrọ ti a fi ohun orin na kọ, nipasẹ eyiti a le fi mọ bi mimọ ni tabi aimọ ni. L' oju mi, isin Ọlọrun ni sakani wa nihin ko gbilẹ gẹgẹ bi isin imale, ati pe ọpọlọpọlọ awọn abọriṣa li o wa ti a ko i ti yi l' ọkan pada s' ọna igbagbọ. Iṣoro -pataki ti mo ṣakiyesi ni pe, nigbati a mu isin Ọlọrun wa fun wa, agba a kannri pẹlu aṣa ilu nibiti wọn gbe ti mu u wa ti awọn ti o mu u wa fi kọ ni. Ṣugbọn eyi ko ri bẹ ni ilu orilẹ-ede miran. A gbọ wipe ni ilu Abysinia, nwọn gba isin mimọ Ọlọrun pẹlu aṣa ilẹ wọn, gbogbo ilu wọn fẹrẹ d' onigbagbọ. Titi di oni yi, ilu Bata ni wọn fi nsin ninu ile Ọlọrun wọn, lai yi aṣa ilẹ wọn pada. Ohun elo orin ti awọn baba nla wa fi nsin oriṣa, ti wọn si fi nṣ' àriya, gẹgẹ bi Bata, Bẹnbẹ, Batakoto, Gangan, Dundun, Konkolo, fere, Molo ati ọpọlọpọ ti nko ni ṣe 'yọnu lati ma to lẹṣẹ-sẹ, a pa wọn ti, nitoriti a ro pe wọn ko jẹ ohun elo mimọ lati fi sin Ọlọrun gbogbo ẹda; nitorina a mu elo ohun orin ti ilu ajeji wá fun wa, gẹgẹ bi *Accordion, Flute, Harmonium, Guitar, Violin, Organ* ati oriṣi miran, eyiti nwọn ka si mimọ; wọn si bẹrẹ si kọni li orin ni ohun ilẹ wọn. Ṣugbọn a dupẹ pe Ẹmi Ọlọrun ti o gbe inu ẹda nṣiṣẹ tirẹ kẹlẹ kẹlẹ. Ẹmi Ọlọrun na lo gbe Prince Ademuyiwa Haastrup ologbe, dide ni igboro Eko, nigba aiye rẹ, ti o si nṣe iwasu lọpọpọ ode pẹlu orin ni ohun ilẹ enia dudu. Awọn ti o mọ nigbana le jẹri si iṣẹ ribiribi ti o ṣe. Bẹ gẹgẹ ni Eni Ọwọ, J. J. Ransome Kuti, ojiṣẹ Ọlọrun fun Ijọ Ake, ni Abẹokuta, ṣe iṣẹ ribiribi ni sa a kan, o si yi awọn abọriṣa l' ọkan pada s' ọna igbagbọ nipa awọn orin ti nma kọ ni ohun ilẹ wa fun wọn ninu isin opopo ode ati lati igberiko de igberiko. Bi o ti lejẹ pe pupọ ninu orin ti Ẹni ọwọ na nlo, la tẹ sinu iwe orin C.M.S. ni ede

Yoruba, mẹlo ni awọn ara wa ti o wa ninu ijọ C.M.S. mọ ninu awọn orin na. Ṣugbọn mo ro pe Ẹni ọwọ Kuti ni lati ṣọpẹ f' Ọlọrun wipe l' oju ẹmi rẹ, diẹ ninu eso iṣẹ rẹ ti tan de ijọ ọmọ ibilẹ ati iṣọkan gbogbo ẹda; Ao ma ranti iru awọn ẹni bẹ, ti wọn ni ifẹ orin ni ohun ilẹ wa.

Ṣiṣẹ ntẹle ni irohin inu iwe yi, nitori pe awọn baba wa a ma p' owe wipe: "A sare kunkun k' o r' oye jẹ, a-rin gbẹrẹ ni yio m' oye de 'le."

OYENẸYẸ.

---

## AIBUKI LA MỌ, A KO M' ALAPẸPẸ.

Gbadamọsi Macgregor Balogun Khilla Abẹokuta to nṣowo ni Ilugun Station, pe apejẹ nla kan si gbangba ile Isimi rẹ ti a npe ni Ararọmi House, ni Ilugun.

Oripe apejẹ yi latari *Store* nla to kọ lati ṣi lati ma fi ra ja Ekurọ, Epo, ati Cocoa fun awọn Oyinbo MacIver nibẹ.

Apejẹ yi bẹrẹ niwọn agogo mẹfa alẹ titi di agogo mejila oru oṣu *February* 8, awọn enia dabi omi nibe, orişirişi ilu Dundun, fere ati molo wa nibi faji yi ariya yi pọ tobẹ ti Egungun oni-wonwẹnnwẹn ṣere bi arira nibẹ pẹlu. Onjẹ ati mimu tẹ ẹnikẹni lọrun nibẹ. Ao daruko awọn gbajumọ diẹ ninu awọn to wa nibi apejẹ yi, M. M. Animaṣawan, Abọdẹrin, L. A. Johnson, Oluyidi, Ogunbiyi ati ọpọlọpọ ẹlomiran, Ọgbẹni Macgregor yi jẹ ẹni ọlọla, ati ọkan ninu olowo pataki ni igboro Abẹokuta, o jẹ ẹni to le nawo, o fẹran ọmọ enia, a nbẹ Olọrun ko gbe ọwọ rẹ soke ninu owo rẹ.

Oyi biri gboju ọna kan, Ọkọ Tẹjumade.

---

## Mo gbe tana danu Mo gbe miran de.

Ile Egbogi ti a npe ni Iṣẹ Olodumare ti o wa ni ẹgbẹ Iga Oloye Aromirẹ ni Ọbun Eko, kun fun orişirişi awọn Egbogi wọnyi ti o ṣẹṣẹ de :—

Egbogi Kuruna, ati Ọṣẹ rẹ, Egbogi Iṣaka, Jẹdijẹdi, Ela ọmọde, Iba, Ipa ọrẹrẹ ọmọde, Egbogi Ẹda ati Aran Kiniṣa, Egbogi Inu riru iwaşu, ati fun ọkunrin pẹlu, egbogi ki ara ọkunrin le giri (ko ma ye ẹ) ati orişirişi awọn eyiti a ko le daruko tan.

Sare lọ sibẹ, ki ọlọra tirẹ, ọpọkuọyọku ni, bi o fẹ lori, oma dọwọ rẹ o,

"Arun ma jogun, ndagba si ẹlẹda rẹ.".

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

---

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kötu, l' Eko.

---


## ***The Philharmonic Band.***

Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ nwọn, ko kọ iwe si,

*THE SECRETARY,*
c/o Anfani Motors
The Marina Lagos.

---

W' O BI, ENIKEJI, OJU L' ỌRỌ WÀ!!
Maşini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSON ti 16, Ita ọja Ajaşẹ, ni owo ọpọku-ọyọku

---

Ni Ile-iwo orişirişi ọja ti
Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER,
Onişowo ara Jamani ni
Ita 7, Labinjọ, leti Ita William

lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun orin ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi.

Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE
Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE
Awo Abọmafa ENAMELWARES
Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran.
Ẹ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi oṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING) Masses Isin Aro,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon. T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J A Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev S J Gansallo |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J A Leigh |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | | Rev S. A. Pearse |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. J C Cole |
| 7 p.m. | | Rev. J. A Angus |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | Rev. J C Cole |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. Dan. O. Mould |
| 7 p.m. | | Rev. D A Beckley |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | | Bro J. A. Ọlaleye |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E D Ṣodeinde |
| 6.30 p.m. | | Bro. H. T. King |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. Samuel Johnson |
| 4.30 p.m. | | Bro. L. A. Randle |
| 9 a.m. | Araṛemi (Baptist) | Bro. E. A. Ojo |
| 4 p.m. | | Rev. A. A. Puddicombe |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | Bro. J. Bandele |

**BROTHERHOOD**

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Bro. Akiremi Davies |
| 7 p.m. | | Pastor A. Adedeji Iṣola |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodeyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH. (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon Rev. H. A. Lewis

## AU REVOIR!

A most enjoyable evening was spent at a send-off given to Mr. Julius O. Cole by a small group of his friends at Oyin House 8, Ajanaku Street on the 13th inst.

The programme for the evening includes photographs, music, refreshments, address to be presented to Mr. Cole, Toast, Dance, etc.

Mr. Cole who by the time this paper gets to its readers is on the high seas (on Board T.M.S. Adda,) hopes to proceed to Sierra Leone for University Education.

Thanks are due to Messrs. B. A. Mumuney, Alfred A. Adu, and others who are responsible for the success of the evening :—*Communicated.*

"VESTA" SEWING MACHINES.

Nos. 3 and 4 Treadle on sale at No. 13 Ọdufẹgẹ Street, Ọbadina District Lagos.

At a giving-away price.

A call will convince you.

ALHAJI ỌLỌRUN-NI-MBE.
*General Trader*

## SOMETHING TO YOUR TASTE.

MR. J. D. OLAYAHA, Painting Contractor and General Decorator is prepared to undertaken all paint-works of every description to the entire satisfaction of Clients.

He is also an expert in sign-board work: has worked for many important European Firms in town notably, the Firm of P. Z. and also the local P. W. D.

Terms reasonable.

For particulars,

Apply at 16, Mọgaji Lane, Ẹpẹtẹdo,

A trial will convince you.

---

ỌMỌ NI YIO ṢẸHIN DE Ẹ.

"Ẹwa wo" "POSI Alarabara"

Ile Igbẹhin lọdọ J. T. COLE,

Gbẹna-gbẹna ni ita 40, Ofin Canal,

Ihin ko to afojuba

A le gbani ni awin ti a ba san idaji owo.

---

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pills and get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neurasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

"Ajenifuja" Store  VIDAL R. COLE
P. O.Box 201 ; 109  Broad Street Lagos

---

Ọgbẹni H. CAMPOS,

Onişowo ni 7, Campbell, Street L'Eko

ni wai iwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ni tita: Ṣẹrẹkẹ ṣin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni; Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun:

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko

Ohun a jẹ lo mba ni lọ.

---

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja ninu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---

## *ILE EGBOGI TITUN.*

Fun irọrun ati anfani gbogbo awọn ti ngbe Olowogbowo, Ita Balogun, Oke-arin Ọfin, Idumata titi lọ de Victoria Road, a şi ṣọbu egbogi titun kan ni Ita Balogun.

*No. 69, Balogun Street,*

Ṣọbu yi jẹ eka ṣọbu nla ti Filipi ni Ajẹlẹ ati Ita Faji—

*Phillips Medicine Store.*

Egbogi ọjulowo pọ nibẹ.

Ma fi ọpọ silẹ nitosi lọ ra ọwọn ni ọna jijin.

---

PAGIDARI!

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onişowo ni Victoria Road ni wabi-wọsi ohun elo, fun Ọmọge ati Ọmọde-m'ẹṣọ ti o si nta ni ita oloko-o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile oja na, ti a nṣe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi şile kan, sisi, tabi tọrọ.

Egbogi orişi-rişi iwosan oniruuru aisan, Ipara olo-orun, ati aghọgun Jigin-oju, ati nkan mere-mere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jokan irin işẹ ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibẹ ni ọpọku yọku.

Oniru-nru wosiwosi ti a ko le ka tan pọ nibẹ bere ohun-ko-hun ti o ba nfẹ yio pese rẹ fun ọ.

O ngbero laipẹ, lati şi ile Ẹrọ Idan Awoşẹju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Iduumagbo.

Ṣoroko a gbe şeranwo ni igbati o ba şi ibẹ

Irohin ko to afojuba.

*P.O.Box 159*  *Phone 214*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWO."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices




Awo Bata ni opoku oyoku. Kowe sowo yala ni ede Yoruba tabi ti Gesi pelu owo si—

E. B. BEYIOKU-ALASE
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawobata, Eko.

29, Oripasun Lane,
King's Quarter, Isale Eko,
Lagos, Nigeria.

THIS IS TO CERTIFY THAT I have many years' experience in Dirty Window Cleaning, Changing of Plain Window to any colour or kind of Pattern in Flowers cleaning or white washing of wall to any kind as Distemper colour etc. Cleaning and Washing of a Dirty House to new, by Vanish and assorted kinds and Pattern of Colour to Paint House and putty and painting of Corrugated roof to red.

For Terms, etc, apply to the above address.

**Lawani T. Mogaji,**
*General Manager.*

Awon AWO ati IFE jojo ti a so ni "Macaulay m' Oluwa m' Oba." sese de fun tita lodo Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko. Irufe awo ati Ife yi ko wopo. E lo ba orire nyin pade nibe. Kosi bo ti ri ni.

## Ogbeni ERIC JOS. W. LEWIS.

Je eniti o gba iwe-ase Ogun pipo, o si "Saba" Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ogbeni J. L. Williams Ologbe, ati si 34 Ita Obadina l'Eko Ogbeni na setan lati da enia lohun lona ise re.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m  2 p.m de 8 p.m
Ni ojo ose lati 6.30 a.m de 8.30 a.m
Owo to ngba ko ta enia lara, e lo bewo,
Ogun re jire.

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awon RECORDS to nkorin lede YORUBA po to wobu ni Ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti ne' oku l' orun?
Ki la ti ne' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbe?

Opokuyoku si ni, wa sa eyi to wu o ni:—

8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.